**IDEA, EDITING, DESIGN:**
Inge Dehennin, Roland Perry, Dora Scott, Nic Smol

**ILLUSTRATIONS:**
Daniel Apolônio Silva de Oliveira, Bart Braeckman, Alcides Sánchez-Monge

**EDITING ILLUSTRATIONS:**
Inge Dehennin, Xue Qing

**TEXT:**
Yao Kolombia Adjiguita, Daniel Apolônio Silva de Oliveira, Wim Bert, Bart Braeckman, Wilfrida Decraemer, Eduardo de la Peña, Godelieve Gheysen, Toon Janssen, Tina Kyndt, Lidia Lins, Lisa Mevenkamp, Tom Moens, Dieter Slos, Nic Smol, Hanne Steel, Nicole Viaene and Wim Wesemael


**TRANSLATED INTO YORUBA BY:**
Gbenga Olaiya and Dr. ‘Biodun Claudius-Cole, Ibadan University, Nigeria

**PUBLISHER:**
Nematology Coordination Office - Ghent University (2024)

NEMEDUSSA
Belgium
partner in development
vliruos
SHARING MINDS, CHANGING LIVES
Co-funded by the Erasmus+ Programme of the European Union
GHENT UNIVERSITY
Agro- and Environmental Nematology
INTERNATIONAL MSC
RECTE SAPERE FONS

# From A to Z,

## nematodes colour our lives!




Colouring book and stories about nematodes

Láti ìbẹ̀rẹ̀ A dé Z, ni à ń rí ìfarahàn aràn nínú ìgbé-ayé wa!

Aràn mùjẹ̀-mùjẹ̀ (aràn inú pupa roboto), aràn kìnnìsà (funfun kékèké) aràn látan-látan (funfun tẹ́ẹ́rẹ́) aràn irúgbìn,oríṣiríṣi aràn: Ta ni ó ti gbọ́ nípa wọn rí?

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ènìyàn péréte ni ó mọ̀ nípa wọn, ibi gbogbo ni wọ́n wà, wọ́n si pọ̀: Láàrin èrùpẹ̀ lábẹ́ àtẹ́lẹsẹ̀ rẹ̀, nínú odò nlá àti ní òfurufú!

Aràn lè kéré jọ́jọ́ wọ́n sì lè tóbi kí wọn ó gùn tó mítà kan. Ohun tí a fi ń dá wọn mọ̀ ni ọṣẹ́ tí wọ́n máa ń ṣe fún irúgbìn láti dènà síso èso, wọ́n sì tún máa ń fa àìsàn fún àwọn ẹranko àti ènìyàn. Àmọ́ sá o, ọ̀pọ̀ aràn ni ó wúlò fún ìgbé-ayé, fún síṣe òsùnwọ̀n erùpẹ̀ àti ìníyelórí omi pẹ̀lú níní òye ìgbésẹ̀ ọjọ́-orí.

Òwé yìí, tí àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ nípa aràn ṣe, yóò sí ojú rẹ sí ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìwàláàyè aràn, yóò sì ṣàfihàn ìbẹ̀rẹ̀ ‘A’ dé òpin ‘Z’ okùnfà bí àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì ṣe wòye ẹ̀dá yìí gẹ́gẹ́ bi ohun tí yóò gbadùn mọ́ ni àti èyí tí a ó nífẹ̀ẹ́ sí láti mọ̀ nípa rẹ̀!

# Astronaut

# Àwọn onímọ̀ nípa bí a ṣe ń rìn ìrìn-àjò òfurufú

Bí àwọn onímọ̀ nípa bí a ṣe ń rin ìrìn-àjò òfurufú bá wà ní òfurufú fún ìgbà pípẹ́ àárẹ̀ máa ń bá isan ara wọn èyí sì lè ṣe okùnfà ìpalára lásìkò síṣe àmúṣe ìgbèrò wọn. Ẹ̀yà aràn kan tí ó máa ń gùn tó mílímítà kan ni ó rọrùn fún àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì láti mú lọ sí inú òfurufú, àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì mú ẹ̀dá kékeré yìí lọ sí inú òfurufú láti lò ó gẹ́gẹ́ bí àwòta àpẹẹrẹ láti túbọ̀ ní ìmọ̀ sí i nípa àárẹ̀ isan ara.

Àwọn aràn yìí sì kúkú móríbọ́ nínú ìjàmbá lílọ bíbọ̀ inú òfurufú kólómbià ní oṣù kejì ọdún 2003 wọ́n bá wọn láàyè nínú ìjàmbá tí ó sẹlẹ̀ sí ohun-èlò tí a fi ṣe wọ́n lọ́jọ̀ ni asálẹ̀ Teṣan. Àwọn ọmọ tí ó jáde láti ara aràn yìí ni wọ́n tún fi sọwọ́/ránnṣẹ́ sí inú òfurufú padà ní 2011. Ògbà yìí ni aáyan láti ṣe ìwádìí ìjìnlẹ̀ nípa bí àárẹ̀ ti máa ń bá iṣan ara tó kẹ́sẹjárí.


NASA
C. elegans

# Beach


# Bèbè-odò/Etídò

Njẹ́ o wòye pé erùpẹ́ bèbè odò dàbí ẹni pé ó wà ní òfo tàbí pé kò ní ẹ̀mí nínú?  dára o, bí nǹkan ṣe hàn sí ni lè mú ẹ̀tàn lọ́wọ́!

Ní abẹ́nú aṣọ ìnura lẹ́yìn ìwẹ̀ rẹ̀, àwọn aràn kékèkè a máa rìn wọ̀lọ̀-wọ̀lọ̀. Nígbà mìíràn, bí ó bá kọ́ ilé yèèpẹ̀ tí a gbẹ́ ilẹ̀ ní tìbù-tòòró ní mítà márùn-ún, márùn-ún, ó gbọ́dọ̀ mọ̀ pé ó ṣe é ṣe kí ó ti dá àádọ́ta mílíọ̀nù aràn lágara. Kì í ṣe oríṣìí kan náà, ṣùgbọ́n ó lè jẹ́ oríṣìí bí àádọ́ta tí kò papọ̀!

Àwọn aràn yìí a máa gbé nínú ẹrẹ̀, àìfojúrí, lọ́pọ̀ yanturu àti láàrin ara wọn.

Bẹ́ẹ̀ ni, ohun iyanilẹ́nu máa ń sẹlẹ̀ lábẹ́nú aṣọ ìnura ìwẹ̀ rẹ̀, ó lè jọ ni lójú bí àwọn aràn ṣe wà ní ilẹ̀ olóoru Áfíríkà tí ó kún fún kìnìhún mọ̀sìà, òtòlò ati bẹbẹ lọ ó kàn jẹ́ pé wọ́n tín-ín-rín jọjọ.


Apolônio


# Compost

# Ajílẹ̀

Ajílẹ̀ ni èémí ìyè kíkún!

Kòkòrò àìlè-fojúrí bákítéèríà. fọ́ngáì, tata-gànràn, aláǹtakùn, ọ̀kùn, ọ̀kùnmọ̀kà àti aràn máa ń sisẹ̀ pọ̀ láti mú kí ìgbọ̀nṣẹ̀ jẹrà kí ó sì fi àwọn ohun ìníyẹlórí inú rẹ̀ pamọ́. Àwọn kòkòrò àìfojúrí wọ́nyí kéré débi pé o kò lè fi ojú lásán rí wọn. O ní láti lo awò tí ó ń mú nńkan tóbi lójú ẹni tàbí irinṣẹ́ tí ó lè mú ni rí ohun tí a kò lè fi ojú lásán rí. Sìṣètò ohun èlò ìṣelọ́jọ̀ ajílẹ̀ sí inú oko-ọgbà rẹ yóò wúlò nítorí pé o lè sọ ewébẹ̀, èso àti àwọn ohun tí a rò pé kò wúlò nínú oko-ọgbà di ajílẹ̀ tí ó níye-lórí. Bí ó bá fi ajílẹ̀ yìí sí ibi tí ó ti ń ṣe ọ̀gbìn, àwọn ọ̀gbìn náà yóò dàgbà dáadáa.

Ọ̀nà pàtàkì láti mú kí àṣetúnṣe wáyé nìyí àbí bẹ́ẹ̀kọ́?



# Deepsea

# Ibú òkun

Ní ìsàlẹ̀ ibú omi kò sí òye ìmọ́lẹ̀ níbẹ̀, èyí ni ó mú kí àwọn ènìyàn máa rò ó fún ìgbà pípẹ́ pé a kò lè rí èémí-ìyè níbẹ̀.


Àmọ́ sá, kò sí ohun tó kọjá òtítọ́!

Ẹja aládìídùn tí ó ní àwòmọ́ pípèsè ìmọ̀lẹ̀, àwọn ẹja nlá nlá tí ó ní eyín, àwọn alákàn kékèké, ẹja tí ó dàbí ìràwọ̀ àti ọ̀pọ̀ àwọn ẹranko mìíràn tí ń lúwẹ̀ẹ́ nínú alagbalúgbú omi òkun.

Bákan náà ni àwọn aràn nífẹ̀ẹ́ ibẹ̀. Pẹ̀lú àwọn àrà ọ̀tọ̀ àbùdá wọn, àwọn jomi-jòkè, wọ́n lè wà láàyè nínú òkùnkùn láìní ojú.

Wọ́n máa ń lò ó láti mọ ibi tí oúnjẹ wà, ẹni tí ó jẹ́ ọ̀rẹ́ àti àwọn ọ̀tá wọn.

O ò rí i wí pé, ọ̀pọ̀ nǹkan tí èèyàn nífẹ̀ẹ́ sí láti ṣàwárí ni ó kún inú ibú òkun.



Apolônio

# Elephant
# Erin

Nj̣é o mọ̀ pé aràn mùjẹ̀-mùjẹ̀ lè mú kí ó rí bí erin? Òròyìn ayọ̀ fún àwọn olólùfẹ́ erin? Kì í ṣe bẹ́ẹ̀!

Okùnfà kí ènìyàn rí bí erin jẹ́ ọṣẹ́ láti ọ̀dọ̀ àwọn aràn mùjẹ̀-mùjẹ̀ kékèké. Àwọn aràn kékèké wọ̀nyí máa ń gbé nínú òpónà ẹ̀yà ẹ̀jẹ̀ funfun nínú àgọ́ ara wọn sì máa ń dí òpónà náà, kí àwọn omira má ba à ráyè kọjá. Èyí a máa ṣokùnfà ara wúwú, tí yóò mú kí àwọn ẹsẹ̀ wa dàbí ti erin (oníjàkútẹ̀)

Nj̣é kò ta ko làákàyè?



# Fossil

# Fosaili/Gbandikan

Àwọn aràn ti wà láyé nígbà tí ọ̀pọ̀ àwọn ẹranko tí a kò gbọ́ nípa wọn mọ́ ti ń sẹ̀mí. A mọ èyí nítorí pé a rí aràn nínú àwọn oje igi kọ̀lọ̀bọ̀ àtijọ́-tijọ́. Àwọn oje igi ìgbà láéláé yìí ń ṣe ààbò lórí àwọn aràn dáadáa. Àwọn oje wọ̀nyí ni a lè tún pè ní ikunmú igi. (ikunmú apádò).

A ń rí àwọn kòkòrò nínú oje igi wọ̀nyí, àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì ṣàwárí aràn nínú àwọn kòkòrò náà, wọ́n sọ fún wa pé láti ìgbà láéláé ni aràn ti jẹ́ máyàmí fún àwọn kòkòrò náà.


A kò tí ì mọ ẹni tí ó ṣe aràn síbẹ̀, ṣùgbọ́n a lè fi dá ara wa lójú pé inú ibú òkun ni aràn àkọ́kọ́ ti ṣe ìṣẹ̀mí.



# GMO

## (Àwọn) ẹ̀dá tí ímọ̀ sáyẹ́nsì tí ìyàtọ̀ bá ìẹ̀sda wọn

Àwọn wọ̀nyí ni ẹranko, irúgbìn tàbí àwọn ẹ̀dá tí ó ní ìrísí kékèké nínú èyí tí àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì ṣe àfikún ìpin àjogúnbá mìíràn sí orí àwọn èyí tí ó ti wà tẹ́lẹ̀ nínú ìdásẹ̀ẹ́. Ní irú ọ̀nà báyìí irúgbìn tàbí èso lè jẹ́ dídáàbò bò lọ́wọ́ oríṣirísị àrùn láti ipasẹ̀ aràn àti àwọn kòkòrò àìfojúrí mìíràn bẹ́ẹ̀. Nítorí náà a kò fi gbogbo ara nílò òògùn apakòkòrò nínú iṣẹ́ àgbẹ̀. Èyí sàn fún àyíká wa àti ètò ìlera wa!


Apolônio

# Hitchike


# Òrìn-àjò lọ́fẹ̀ẹ́

Ọ̀pọ̀ àwọn aràn ni ó gbọ́n púpọ̀.

Àwọn aràn inú igi igbó a máa tipasẹ̀ kòkòrò yánnibó fò láti ara igi kan sí òmíràn. Àwọn kòkòrò yìí a máa gbé ihò kékèké sí ara igi láti wá oúnjẹ fún ara wọn àti láti yé ẹyin. Ihò yìí ni àwọn aràn máa ń lò láti dé ibi tí omi àti oúnjẹ wà nínú ẹ̀yà ara igi.

Níbẹ̀ ni wọ́n ti máa ń rí àyíká tí ó dára láti bí sí i ṣùgbọ́n lẹ́yìn ìgbà díẹ̀ wọn yóò tún di ojú òpó náà padà, èyí a máa mú ki igi di aláìlókun ni ara ó sì lè padà kú. Kòkòrò yánníbo yìí a máa ṣe ìrànwọ́ fún aràn àti  àrùn láti fọ́nkálẹ̀.

Ó ṣe ni làáànú pé, àwọn kòkòrò tí ìrí wọn fanimọ́ra tí wọ́n jẹ́ onírìn-àjò ọ̀fẹ́ yìí jẹ́ ewu ńlá fún àwọn igi ìgbẹ́ káàkiri àgbáyé.




# Insect

# Kòkòrò

Nígbà mìíràn àwọn kòkòrò lè mú ni bínú. Wọn a máa gbé ihò sí ara èso wa wọn a sì máa pa igi lára.

Dídára ibẹ̀ ni pé, àwọn aràn kan wà tí ó máa n ràn wá lọ́wọ́ láti bá àwọn kòkòrò yìí jà. Bí aràn bá wà ní kékèké, wọn a máa wọ inú àwọn ẹyin kòkòrò. Àwọn kòkòrò àìfojúrí tí ó wà nínú àwọn aràn kékèké yìí, a máa di púpọ̀ nínú ẹyin wọn, tí ó máa ń pèsè oúnjẹ fún àwọn aràn. Àwọn aràn náà yóò máa dàgbà sí i wọn yóó sì máa pọ̀ sí i títí wọn yóò fi di ẹgbẹlẹ́gbẹ̀ nínú ẹyin, èyí ti yóò jẹ́ kí ẹyin náà di òbu.

Ní ọ̀nà yìí a le dáàbò bo àwọn èso tí aràn bá wà nínú wọn láìlo kẹ́míkà. Èyí ni à ń pè ní èyí tí kì í ṣe ààtọwọ́dá.




# Jungle

# Igbó tó díjú (Aginjù)

Awọn aràn ẹranko a máa sábà lọ́júpọ̀ pẹ̀lú ìgbésí-ayé tí ó jẹ mọ́ ìrònújinlẹ̀. Wọn a tilẹ̀ máa lo onírúurú àwọn ẹranko láti mú wọn dé ibi tí wọ́n ti gbà wọ́n lálejò kí wọn ó lè parí ìgbésí ayé wọn.

Àpẹẹrẹ ìyàlẹ́nu ni ti aràn tí ó máa ń ṣe ọṣẹ́ fún aláǹtakùn, tí ó máa ń gbé ní àwọn agunjù gúúsù Amẹ́ríkà àti irú àwọn aginjù bẹ́ẹ̀ tí wọn ń gbé nínú àwọn ìgbọ̀nsẹ̀ ẹyẹ. Àwọn ìgbọ̀nṣẹ̀ ẹyẹ yìí jẹ́ oúnjẹ fún aláǹtakùn, nítorí náà ni àwọn aràn ṣe máa ń bá ara wọn nínú ikùn aláǹtakùn. Àfòmọ́ ni aràn jẹ́ yóò sì máa dàgbà nínú aláǹtakùn. Ikùn aláǹtakùn yóò bẹ̀rẹ̀ sí í wú yóò sì máa pa àwọ̀ dà: àwọ̀ ara yóò yípo sí dúdú láti pupa tí ó mọ́lẹ̀ èyí tí yóò mú kí alántakùn rí bí èso bẹ́rì (ìyeyè pupa)!

Àwọn ẹyẹ fẹ́ràn èso (bẹ́rì) yìí, léyìí tí ó máa ń mú kí alántakùn wọ́jú gẹ́gẹ́ bí ìjẹ fún ẹyẹ. Àwọn ẹyẹ á jẹ aláǹtakùn wọn á sì túbọ̀ mú ìtànkálẹ̀ bá àwọn aràn tí ó jẹ́ àfòmọ́ nínú ìgbọ̀nsẹ̀ wọn: Ní ọ̀nà báyìí ètò ìgbé-ayé aràn yóò parí.


Apolônio

# Kid

# Ọmọdé


Njẹ́ ìdí máa ń hùn ọ? Bóyá o ní aràn látan látan? (aràn funfun tẹ́ẹ́rẹ́ kékèré)

Aràn látan látan a sáábà máa yọ àwọn ògo wẹẹrẹ lẹ́nu. Àwọn abo aràn yìí ni ó máa ń gbé inú ìfun èniyàn. Bí ó bá di alẹ́ wọ́n máa ń yé ẹyin wọn sí ẹ̀gbẹ́ ẹnu ìhò-ìdí níbi tí afẹ́fẹ́ àmísínú tí ẹyin wọn nílò láti dọmọ máa ń wà.

Bí aràn ṣe máa ń rìn wìnnì-wìnnì ni ó ń ṣokùnfà ìdí yíyín. Bí o bá wá bẹ̀rẹ̀ sí í họ ọ́, àwọn ẹyin náà á bẹ̀rẹ̀ sí í  pọ̀ sí i  láti ọmọlẹ̀ sí ọlẹ̀.

Nígbà tí ọmọdé bá fi ọwọ́ ti ọlẹ̀ yìí ti wà sí ẹnu rẹ̀, ẹyin yóò jẹ́ gbígbémì àrùn yóò sì wáyé.

Nítorí náà, ẹ̀yin ọmọdé, ẹ máa fọ ọwọ́ yín!!!



# Love
# Ìfẹ́

Gbogbo ẹ̀yà aràn ni ó ní ọ̀nà tí wọn ń gbà lòfẹ́. Ọ̀pọ̀ àwọn ẹ̀yà aràn ló máa ń ṣe bẹ́ẹ̀ bí ènìyàn. Bí akọ wọn ti ṣe wà bẹ́ẹ̀ náà ni abo wà tí ó máa ń bí ọmọ tuntun.

Nínú àwọn ẹ̀yà mìíràn a lè rí àwọn àkàndá. Èyí ni ẹnìkọ̀ọ̀kan tí ó ní ìṣẹ̀dá akọ àti abo papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà ti wọ́n sì ní ìkapá láti pèsè ọmọ fúnra wọn.

Nígbà mìíràn kò ní í sí abo rárá. A kàn lè rí àkàndá tí ó ní ìṣẹ̀dá takọ-tabo (tí ó lè pèsè ọmọ fúnra rẹ̀) àti ní ẹ̀ẹ̀kọ̀ọ̀kan a lè rí èyí tí akọ bá ní àṣepọ̀ (ìbálòpọ̀ takọ-tabo). Àwọn akọ a sì máa bá àwọn àkàndá tí ó ní ìṣẹ̀dá takọ-tabo wọ̀nyí ní ìbálòpọ̀ lẹ́yìn tí wọ́n bá dùn mọ́ ara wọn.



Movemenet

# Lílọ bíbọ̀ (Ìrìn)

Àwọn aràn kó fágá. Ọ̀pọ̀ wọn máa ń rìn bí ejò, wọ́n máa ń sáré rìn bí ìgbà tí òwú gba inú abẹ́rẹ́ kọjá tàbí bí ìgbà tí nǹkan ń lọ òkè lọ ilẹ̀, wọ́n á máa lo ipá wọn láti nà bẹ̀rẹ̀ láti orí dé ìrù.

Ọ̀pọ̀ wọn lọ́ra, ṣùgbọ́n àwọn mìíràn yára púpọ̀. Ní ọ̀nà báyìí o lè mọ ẹ̀yà ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn bí wọ́n ṣe ń rìn.

Òwọ̀n péréte èyí tó kúrú àti aràn tí ó tóbi pẹ̀lú ẹ̀yà tí ó kéré jù nínú ara wọn bí ọwọ́ àti ẹsẹ̀ máa ń ṣe yàtọ̀ sí ara wọn; wọn a  máa lo ẹ̀yà ara wọn yìí bí òpó tí wọ́n sì ń rìn bí i katapílà.



# Nobel prize


# Àmì ẹyẹ àgbáyé Nobel

Ẹ̀yà aràn roboto tí ó máa ń wu ni láti wò ni ó gbajúmọ̀ jù láàrin àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì. Wọ́n ti ṣe àmúlò rẹ̀ láti wá ìdáhùn sí ọ̀pọ̀ ìbéèrè nínú ìmọ̀ sáyẹ́nsì ìgbé-ayé.

Fún àpẹẹrẹ, báwo ni ẹ̀yin ṣe máa ń ní ìdàgbàsókè láti di aràn? Báwo ni aràn ṣe máa ń gbóòórùn oúnjẹ tàbí báwo ni wọ́n ṣe ń rìn wọ̀lọ̀-wọ̀lọ̀?

Ní àwọn ọdún díẹ̀ sẹ́yìn orísìí àwárí ọ̀tun-ìmọ̀ pàtàkì ni ó ti jẹ́ sísẹ àti sísẹ agbéǹde ọ̀nà tuntun láti ṣàwárí ọ̀tun-ìmọ̀ nípa lílo aràn kékèké.

Àwọn àwárí ọ̀tun-ìmọ̀ wọ̀nyí ṣe pàtàkì débi pé láàrin ọdún 2002 sí 2013, àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì mẹ́fà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wọ́n sisẹ́ lórí irúfẹ́ aràn yìí ni wọ́n gba àmì ẹ̀yẹ̀ àgbáyé.


NOBEL
PRIZE
Apolônio

# Ocean


# Òkun

Kòṣémánìí àti nǹkan pàtàkì ni òkun jẹ́ sí ènìyàn. Ó ṣeni láàánú pé a kì í fi bẹ́ẹ̀ ṣe àmójútó tó yẹ fún-un. Epo, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀gbin ati àwọn nǹkan tí ó ń ṣe àkóbá fún ẹ̀yà-ara ni a máa ń rù dà sí òkun.

Òrètí wà pé, ìṣe yìí ni ipa pàtàkì lórí àwọn ẹranko tí ó ń gbé ibẹ̀. Bí ọ̀pá epo bá fọ́ lójiijì yóò di májèlé sí inú omi, gbogbo ẹranko tí ó ń gbé ibẹ̀ ni yóò sì fẹ́rẹ̀ ẹ́ gbẹ́mìí-mì tán, àfi àwọn aràn.

Àwọn aràn ní ẹ̀dá tí ó pọ̀jù lọ tí ó ń gbé ìsílẹ̀ omi onírúurú wọn ni ó sì wà níbẹ̀. Àwọn mìíràn ní ìfaradà ìdàrúdàpọ̀ tí ó lè wáyé, bí i ọ̀pá epo fífọ́, àwọn mìíràn sì lè fi ara dà á. Àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì ṣàwárí pé ọ̀pọ̀ àwọn aràn ni ó lè ṣèrànwọ́ láti pá oró epo tí ó lè ṣe àkóbá fún ìgbé-ayé.

Nípa báyìí, ìwádìí síṣe nípa àwọn aràn sọ fún wa púpọ̀ nípa ewu tí ó máa ń wáyé láti ara ìdàrú-dàpọ̀ abẹ́ omi, àti pẹ̀lú pé ó ṣàfihàn bí àwọn aràn ṣe lè ràn wá lọ́wọ́ láti dẹ́kun irú ọṣẹ́ bẹ́ẹ̀ tí àyípadà rere yóò sì bá ibú òkun.



Apolônio

# Potato

# Pòtétò (Anamọ òyìnbó)

Dídín, yíyan àti gígún pòtétò, gbogbo wa ni a fẹ́ràn wọn. Njẹ́ o mọ̀ pé àwọn aràn náà fẹ́ràn pòtétò?

Kòkòrò aràn pòtétò àti nǹkan bìrìkìtì bí òrùka tí ó máa ń wà ní ibi gbòngbò láti ipasẹ̀ aràn a máa wà ní ibi gbòńgbò àti èèbú ọ̀gbìn pòtétò, nítorí ìdí èyí, irúgbìn náà kò ní í dàgbà bí ó ti yẹ, tí ó máa ń jẹ́ kí àwọn àgbẹ̀ ní ọ̀dá pòtétò lásìkò ìkórè. Kòkòrò kìrìbìtì tí aràn máa ń ṣokùnfà yìí a máa mú kí irúgbìn pòtétò kí ó má ṣe dùn-ún wò, nítorí náà àwọn àgbẹ̀ kò ní lè kó wọn lọ fún títà ní àwọn ibi ìtajà.



2011

# Quarantaine

# Ìyàsọ́tọ̀

Ọ̀pọ̀ ẹ̀yà aràn ni ó máa ń mú kí irúgbìn ṣe òjòjò. Léyìí tí yóò mú àdínkù bá ìkórè ewébẹ̀, èso tàbí àwọn irúgbìn jíjẹ mìíràn. Òdàgbàsókè àwọn ọ̀gbìn tí a fi ń ṣe ẹwà pàápàá lè ní ìpalára.

Bí ìfarahàn ẹ̀yà aràn tí ó lè ṣe ìpalára tàbí tí ó léwu bá wà ní orílẹ̀-èdè kan, irú orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ yóò sa gbogbo ipá tí ó bá wà ní ìkáwọ́ rẹ̀ láti fi irú aràn bẹ́ẹ̀ ṣe àwátì. Irú àwọn aràn bẹ́ẹ̀ yóò wà lára àkọṣílẹ̀ ẹ̀yà tí ó wà ní ìyàsọ́tọ̀. Àwọn òṣìṣẹ́ aṣọ́bodè yóò lo irú àkọsílẹ̀ bẹ́ẹ̀ nígbà tí ìkólọ-kóbọ̀ àwọn ohun èlò igbó-ọba àti ìpèsè iṣẹ́ àgbẹ̀ bá ń wáyé. Irú àwọn ohun èlò tí ó bá ní àwọn aràn yìí yóò jẹ́ dídá padà tàbí kí wọ́n dá iná sun wọ́n.


1.
2.
?
?
3.
4.
5.
!
6.


# Retriever dog

# Ajá-ọde

.

Ní inú ajá-ọdẹ, tàbí nínú ajá yòówù, ọ̀pọ̀lọpọ̀ aràn lè farahàn. Aràn-ọkàn, aràn-àyà, aràn-inú àti aràn inú agbẹ̀du. Àwọn aràn yìí a máa bọ́ sí ara ajá láti ara omi ọmú ìyá tàbí láti àyíká. Wọ́n máa ń gbé inú ikùn, àyà tàbí ọkàn.

A kì í sáábà mọ̀ pé ajá ni àwọn aràn wọ̀nyí, ṣùgbọ́n nígbà mìíràn àìsàn nlá lè farahàn bí i kí ẹ̀jẹ̀ máa dà, àìlè mí dáadáa (sẹ́mì-ín sẹ́mì-ín) tàbí àìlóòrìn. Ohun tí ó dára jù lọ láti ṣe ni kí ó rí i dájú pé kí ó máa lo òògùn aràn tí àwọn onímọ̀ ìtọ́jú ohun-ọ̀sìn bá tọ́ka sí fún ajá rẹ̀. Àwọn aràn wọ̀nyí yóò kú, ajá rẹ̀ yóò sì wà láàyè títa kébé àti ní ìlera pípé.


HOND


Soccer

# Bọ́ọ̀lù Àfẹsẹ̀gbá

Àmójútó tí ó mú yányán ni a máa ń ṣe fún orí pápá tí wọ́n ti ń gbá bọ́ọ̀lù. Ojoojúmọ́ ni à ń fi omi wọ́n ibẹ̀ àwọn mìíràn sì ní èròjà tí ó lè mú kí abẹ́ ilẹ̀ lọ́wọ́ọ̀rọ́.

Àwọn àfòmọ́-aràn ara ògbìn nífẹ̀ẹ́ sí èyí! ni ẹnu wọn ihò tóóró bi abẹ́rẹ́ tí ó ní ẹnu ṣóńṣó wà níbẹ̀ tí wọ́n fi máa ń mu omi láti ara egbò àwọn ewéko. Nígbà gbogbo ni ẹgbẹ̀lẹ́gbẹ̀ àwọn aràn wọ̀nyí máa ń wà lórí pápá tí wọ́n ti ń gbá bọ́ọ̀lù.

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ọṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe fún ewéko ní gbèdéke, ṣùgbọ́n tí ó bá jẹ́ ọ̀pọ̀ aràn, àmì tó tò tó yóò dáranjẹ̀ sí ara ewéko láti pa wọ́n run, yóò sì mú kí orí pápá bàjẹ́. Aràn a máa mú inú bí àwọn agbàbọ́ọ̀lù, ṣùgbọ́n aràn kì í fi ojú winá ohun kan lọ́dọ̀ àwọn agbábọ́ọ̀lù.


Apolônio


# Teeth

# Eyín

Bí ọmọdé àwọn aràn kékèké máa ń hu eyin pààrọ̀. Ò máa ń tó ìgbà mẹ́rin kí wọ́n tó hu eyín àgbàlagbà. Láàrin àwọn ẹ̀yà aràn lóríṣiríṣi ìrí eyín yìí máa ń yàtọ̀, ó wà lọ́wọ́ ohun ti wọn ń jẹ.

Àwọn aràn mìíràn, bí i àwọn tí ó máa ń fi kòkòrò mìíràn ṣe  ìjẹ, ní eyín tí ó mú púpọ̀ tí wọ́n fi ń jẹ ẹranko mìíràn. Àwọn aràn mìíràn ni eyín tí ó dàbí àfàmu láti fi fa omi ara egbo irúgbìn mu. Àwọn aràn mìíràn kò si ní eyín rárá! àwọn kòkòrò àìlèfojúrí ni wọ́n máa ń jẹ, mmm...

Ò ní adùn!


Apolônio

# Unique

# Ó yàtọ̀

Nígbà tí ó ń ka ìwé yìí, máa fi ojú-inú wo ìṣẹ̀dá àyíká kan tí ó rẹwà.

Èyí lè jẹ́ gbogbo nǹkan: erùpẹ̀ funfun etídò àti omi òkun aláwọ̀ aró, odò tí ó ń sàn gbùú-gbùú tàbí igbó tí ó tóbi. O sì lè ronú nípa àwọn ẹranko àti igi.

Kì í ṣe dandan ni kí ó jẹ́ ohun kan pàtó ni ó ní lọ́kàn, gbogbo àwọn ibi tí a sọ yìí ni ó ní àwòmọ́ kan tí ó pa wọ́n pọ̀: Àwọn aràn máa ń fi ibẹ̀ ṣe ibùgbé. Wo àwòrán tí ó tẹ̀lé àlàyé yìí, gbogbo ohun tí ó wà nínú àwòrán yìí jẹ́ àyíká irúfẹ́ ẹ̀yà aràn kan. Ó yàtọ̀ àbí bẹ́ẹ̀kọ́?




# V inegar

# Ohun mímu kíkan

Àwọn aràn kékèké tàbí aràn ohun mímu jẹ́ èyí tí ó máa ń ní òmìnira láti gbé ibi tí ó wù ú, wọ́n lè gbé ní ibi tí àyíká rẹ̀ ní èròjà tí ó kó ẹnu: ìsàn-omi, oríṣiríṣi ohun jíjẹ  eléso, ohun mímu aṣaralóore. Nǹkan bí i mìlímítà kan sí ìkejì ní gígùn wọn, wọn a sì máa jẹ àwọn kòkòrò àìlèfojúrí tí ó wà lára àwọn èso àti àwọn ohun jíjẹ àti mímu tí kò tí ì di àṣeparí. Àwọn aràn kékèké jẹ́ oúnjẹ fún àwọn ẹranko mìíràn, ọrá pọ̀ ní ara wọn, fún ìwúlò ọmọ ẹja tí ó máa ń rí bí àwọ̀ òṣùnmàrè, wọn a máa sọ wọ́n di ìjẹ ní ìrọ̀rùn.

Njẹ́  o fẹ́ràn kí o ṣe àrídájú ohun tí ẹnìkan kò tíì ṣe wò kí o sì gbìyànjú láti sọ àwọn aràn kékèké di púpọ̀?

Ó rọrùn púpọ̀: gbogbo ohun tí o nílò ni ìgò tàbí ike omi, àpẹẹrẹ ohun mímu èso ápù tàbí òmíràn, omi, ìdérí, aṣẹ́ àti àwọn aràn kékèké wọ̀nyí láti fi bẹ̀rẹ̀. Wo ìtọ́ni lórí ẹ̀rọ ayélujára kí o sì ... kú oríire!


VINeGAR
Apolônio

# Whale

# Erinmi


Njẹ́ o mọ ìwé kan tí ó dá lórí Moby Dick, ẹja ńlá funfun?

Nínú ìwé yìí ònkọ̀wé ṣàpèjúwe Moby Diẹk gẹ̀gẹ̀ bí èyí tí ó bùáyà, tó máa ń bínú tí ó sì léwu, ó máa n ṣokùnfà òfò oríṣiríṣi nínú odò ńlá.

A lè sọ pé, ìtàn lásán ni, ṣùgbọ́n ẹja ńlá yìí jẹ́ ọ̀kan lára ẹranko tí ó tóbi jù lórí ilẹ̀ ayé, ó tóbi ju ọkọ̀ bọ́ọ̀sì méjì lọ.

Inú ẹja ńlá yìí ni a ti rí aràn tí ó tóbi jù lọ: nǹkan bí i mítà mẹ́jọ ni gígùn rẹ̀ ó sì sanra ní sẹ̀ntímítà méjì àbọ̀!

Nínú ikùn erinmi yìí tí ó jẹ́ abo, ọlẹ̀ àti ẹgbẹ̀lẹ́gbẹ̀ aràn ni ó máa ń wà lórí olubi. Bí o bá mọ̀ bí ẹja yìí ṣe tóbi púpọ̀ tí ó sì máa ń ní oyún fún oṣù mẹ́ẹ̀ẹ́dógún, yóò yé ọ ohun tí ó ń mú kí aràn wọn tóbi bẹ́ẹ̀!



# Xiphinema


# Sìfinimà

Sifinima, orúkọ tí kò rọrùn láti pè!

Njẹ́ o mọ̀ pé àwọn aràn náà ní orúkọ?

Ní ilẹ̀ Gíríkì nígbà láéláé, Sìfí túmọ̀ sí “ìrísí, idà”.


Àwọn aràn jẹ́ àfòmọ́ irúgbìn wọ́n sì ní eyín tí ó rí bí idà. Ìrísí yìí ni ó mú kí àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì yan orúkọ yìí fún irú àwọn aràn náà. Pẹ̀lú eyín wọn yìí wọn á máa wọ inú irúgbìn pẹ̀lú ìrọ̀rùn láti jẹ. Ọ̀pọ̀ àwọn aràn yìí ni ó máa ń ní àrùn lára àwọn àrùn yìí sì lè bọ́ sí ara irúgbìn, yóò sì sọ wọ́n di ọlọ́kùnrùn. Ó dára pé, àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì àti àwọn àgbẹ̀ ti ṣàwárí bí àwọn irúgbìn kò ṣe lè ṣàìsàn.



# Yam

# Ịṣu

Fún ọ̀pọ̀ èèyàn lórí ilẹ̀ ayé yìí, iṣu ni ó jẹ́ orísun oúnjẹ wọn. Ó máa ń dàbí pòtétò ńlá. Àwọn aràn fẹ́ràn láti máa jẹ iṣu. Wọ́n fẹ́ràn rẹ̀ débi pé wọ́n lè bá gbogbo odidi iṣu kan jẹ́, tí wọn kò ní í fi ọ̀kankan sílẹ̀ fún àgbẹ̀ àti àwọn ẹbí rẹ̀ láti jẹ. Ọ̀pọ̀ àwọn aràn máa ń wọ inú iṣu, wọn yóò máa jẹ ẹ́ títí wọn yóò fi tóbi bọ̀ǹbọ̀ tí wọn yóò sì yé ẹyin. Àwọn irúgbìn máa ń ní òye pé àfòmọ́ ti dé ara wọn tí wọn yóò sì ṣàfihàn rẹ̀ nípa síṣe àmì bìrìkìtì bí òrùka yíká rẹ̀. Èyí ni ó fà á tí ọ̀pọ̀ èèyàn fi máa ń pe aràn yìí ní aràn olórùka.


Apolônio

# Zebra

# Ẹṣin-abilà

Ẹṣin-abilà yìí jọ ẹsin ilé ìtàn aládùn sì wà tí ó jẹ mọ́ aràn, ẹsin-abilà àti ẹsin-ilé.

Aràn kékeré kan wà (tí kò ju irinwó mìlímítà) lọ ní gígùn ó máa ń sábà wà lára ẹsin-abilà àti ti ilé látipasẹ̀ egbò tàbí láti ẹnu àti imú. Bí ó bá ti wọ àgọ̀-ara wọn tán wọn yóò lọ sí oju òpó ẹ̀jẹ̀ tí yóò gbé wọn lọ sínú kíndìnrín, ẹ̀dọ̀ àti ọpọlọ níbi tí wọ́n ti máa ń di ọ̀pọ̀ yanturu láìpẹ́ jọjọ o sì lè ṣokùnfà kí ẹran ó túùkàn (gbẹ́mì-ín-mì)

Bí a bá tètè ṣe àkíyèsí kòkòrò àrùn yìí a lè ṣetọ́jú àwọn ẹran náà ni àṣeyọrí, ṣùgbọ́n nítorí pé ènìyàn péréte ni ó mọ̀ nípa àwọn aràn tín-ín-rín wọ̀nyí àti pé wọ́n máa ń bá òògùn apakòkòrò mulẹ̀, ó máa ń jẹ́ kí àwọn ẹranko wọ̀nyí kú.


Apolônio